**Appointmet vacant**

1. Journey Man-Printer
1. Advance Printer

Apply
Modupe Press
16, Bamgbose st
Lagos.

# IROHIN IMỌLẸ

MOTTO: IMỌLẸ DE, OKUNKUN PARADA.

**Notice**

Ẹma polowo oja yin sinu Iwe Irohin Imole.

VOL. III No. 152 MONDAY JUNE 20 — JUNE 26 1960 KỌBỌ KAN (1d)

# Enmo ni opopo Denton ni Iddo, won ri oku enia ninu Apo-Omi (Water Pipe)

AWON OLOPA INU Eko ri ise pataki ti o kanpa se ni Iddo ni ojo Eti ti ise ojo Ketadinlogun osu yi. Kilo fa ise kanpa yi? a mo wipe enyin onkawe wa yio bere.

OHUN TI O FA NI WIPE WỌN RI OKU ENIKAN NINU APO (PIPE) OMI L'ẸBA IBUSO MỌTO NI IDDO.

Wọn ri atni ti o jọ wipe bi ti ẹnipe a fi nkan ṣa ni lara, ni ara oku yi, ọpọlọpọ ọgbẹ ni ori, oju, ati ọwọ oku na. Sokoto dudu ti o ti reri fun omi ni a ba lara oku yi.

Ọga awọn Ọlọpa kan sọ fun onirohin wa kan wipe, awọn ri firi pe nṣe ni wọn pa ẹniti o ku na, atipe ipakupa ni wọn si pa a. Ko ti si ẹniti o mọ enia ti o k u yi jẹ, a si gbọ wipe awọn oṣiṣẹ Costain ti o nṣiṣẹ Omi ni Iddo ni wọn ri oku yi. Wọn ti gbe oku yi lọ si ile-lakulaku, lati la-a, ki wọn ba mọ ohun ti o pa.

Lẹsẹ kẹsẹ ti wa-a-wu ti a gbe oku, a ri oku, ti lọ silẹ ni awọn Ọ l ọ p a inu ti bẹrẹ iṣẹ iwadi. Awọn ẹka kan ti olori wọn jẹ Albert Ench, ni wọn yi ibusọ mọto ni Iddo ka, ti wọn si nwa ohun ti o le fihan nkan ti o fa iku ologbe yi. Awọn ẹka imiran kẹ ti olori wọn jẹ J. O. Nnamani tun yi agbegbe Ebute-Mẹtta ka titi de ibiṣe Leventis ni Oyingbo ti wọn si nṣe iwadi bakanna.

A gbọ wipe o di awọn enia mẹfa ti awọn ọlọpa pe pe ki wọn wa fun ibere nipa ọrọ yi, ṣugbọn a gbọ wipe ko si ẹniti o mọ enia ti oku yi jẹ ninu. nwọn Awọn ọlọpa dẹ ti da wọn silẹ.

## Omo Obirin kan ji aso gbe nitori Oko re.

Ọdọmọbinrin ọmọ ọdun mọkọdinlogun kan ti oruko rẹ njẹ Modupẹ Elegbede, ti ongbe No 5, Ewumi Lane, ni Isalẹgangan L'Eko ni A d a j ọ da lebi lori ẹsun Ole igara ti awọn Ọlọpa fi sun u. Ninu ejọ ti wọn ro niwaju Adajọ awọn Ọlọpa fihan gbangba pe Ọdọmọ-binrin Ole yi jẹ Oṣiṣẹ Ile Iṣẹ kan L'Eko ti oruko rẹ njẹ Ikorodu Trading Company, ati wipe ninu osu kini ọdun yi. ni ọdaaran Obinrin yi ji Aṣọ Suwẹta (Sweater) Mẹdogun (15) ti iye owo wọn jẹ Pọuu Mẹsan £9) ni o ji gbe awọn oniṣẹ Ikorodu Trading Company lo ni awọn Suweta na. Awọn Ọlọpa tun rojọ wipe ko si ẹniti iba mọ ohunkohun nipa ọrọ Suwẹta yi bi ko ba si ti Ọga kan ni ile iṣẹ yi ti ori Suwẹta yi ninu Sọbu kan ni titi ọna Apapa niwọnba igbati o si jẹ wipe a ko ti ta Suwẹta yi fun ẹnikẹni bi o ṣe de inu Sọbu yi ki yio sai ya ẹnikọni lẹnu.

Ni ọga yi ba lọ kọ moko-moro fun Ọga Agba ile iṣẹ na ti eleyi ni si lọ sọ fun awọn Ọlọpa.

Nigbati awọn Ọlọpa ki baba Onisọbu molẹ gira, oni ki wọn ṣe on jẹjẹ wipe enia ni ota wọn fun on. Loba mu wọn lọ si ile ọmọde binrin ọdaran yi. Ọmọdebinrin wi si awọn Ọlọpa wipe on ni o ta fun, onisọbu na, ni Ọlọpa ba fi ẹsun ole igara lọ.

## Oni yio gba Oye re gegebi Gomina ni ojo kejo osu July

GOMINA titun ti ao fi jẹ ni Ipinlẹ Iwọ Orun Ọlọla Alaiyeluwa Adesoji Aderẹmi ni yio gba oye rẹ titun ni ọjọ Ẹti ti nṣe ọjọ kejọ osu July.

Ile-Iṣẹ Olotu I j ọ b a Ipinle Iwọ Orun, fi ikede kan si ita wipe awọn ti nṣe eto nipa tifi joye Ọni gẹgẹbi Gomina ati ti filọ ti Ọlọla John Rankine, ẹniti o jẹ Gomina ni Ipinlẹ na nisisiyi.

Ni ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ kini osu July, Oloye S. L. Akintọla, Olotu Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun yio se ase nla kan f u n Ọlọla Rankine ni ile isimi Lafia. Ni ọjọ keji, gbogbo Ọba Ipinlẹ na yio se ase irọlẹ ni ile Aṣofin ti Ipinlẹ na. Awọn ọmọ ẹgbẹ Aṣofin ati ọpọlọpọ enia jankan jankan ni yio wa nibẹ.



Alaiyeluwa Adesoji Aderẹmi Ọni ti Ile-Ifẹ

Ikede yi sọ wipe o dun Ijọba pe Ọlọla Rankine ko le se ibewọ ti o ti fẹ se jakejado Ipinlẹ mọ, nitoripe kosi asiko. Ikede yi wa sọ wipe eto mbẹ ti a nse lati jẹki awọn olukuluku Ijọba Ibilẹ wa ṣe idagbere fun Ọlọla ati Iya-Afin Rankine. Ọlọla John Rankine ti a loro wipe yio fi Naijiria silẹ ni ọjọ keje osu July ni a gbọ wipe yio ṣe ibẹwo si Abeokuta, Ijebu Ode, Ọyọ, Oshun.

Rankine yio fi Ibadan silẹ fun Eko ni ọjọ karun oṣu July, yio si woko lati lọ si ilu Oyinbo ni ọjọ keje oṣu July yi kanna.

# OLOFOFO

Lati Ọwọ:—" ỌMỌ ADE"

MO KI YIN GBOGBO ẸNYIN Okawe Irohin Imọlẹ Oluwa ko ni jẹki Kọbọkọbọ ki o wọn yin, ẹ o si ma ri ṣe, ṣugbọn bi ti Ole kọ, ẹniti ko ni'ṣẹ lọwọ Oluwa yio pese fun. Paapa gẹgẹbi ileri ti Ọgbẹni Ṣhoyinka ti ṣe wipe on yio tubọ mura si iwe on ni kikọ nigbagbogbo, bakanna si ni Omidan M. A. Adebayọ ti fi ọwọ sọya fun Olotu Irohin Imọlẹ wipe ni Oṣu July ọdun yi lagbara Odua on yio bẹrẹsi ma gbe Itan Aladun orişirişi eda ati Ọgbẹni Falana Opitan inu Ẹrọ Redio tẹlẹ ri.

Mo si wadi lati ẹnu Olotu Irohin Imọlẹ pe nigbati Iwe yi yio di oju Ewe Mẹfa pe ṣe ko ni fi Owo kun owo rẹ. Idahun Olotu si nipe owo fifi kun, ko ti ya ni kiakia yi nigbakigba ti on yio ba fi owo kun on yio jẹki gbogbo awọn Okawe mọ jake-jado.

ILARA NI EYI TABI KẸNIMANI?

Pupọ igba ni mo ti nṣe Akiyesi wipe ti awọn awa-Mọto ba wa Mọto kọja, ti o tẹ Fere fun awọn ti o wa lọna ni nwọn ma npe wọn pe"A GO DRIVE MY SELF" lọ gba DẸRẸBA. Ah! ẹnyin ti ẹ nsaba sọ irufẹ ọrọ bẹ, ẹranti pe' Ọlọrun ko gbagbe ẹnikan, emi yio si sọ idirẹ fun yin ti awọn A go DRIVE MYSELF ko ṣe saba gba DẸRẸBA nipe ilosi DẸRẸBA MIRAᐟ ti lẹ buru ti ko ṣe f'ẹnu sọ nitori ohun ti o ṣe emi papan ni.

Lọna kini boya iwọ ti o ni moto ya owo ra moto na ni tabi o ko ya owo, dẹrẹba miran ko tilẹ fẹ mọ ju pe ko wa ni iwakuwa, ti o ba si ba sọ ju, si sọ ni yio sọ kọkọrọ mọto rẹ si o. Ọna keji, dẹrẹba miran a ma gba abọdi lati ọwọ iyawo oni mọto, ni pa gbigbe iyawo rẹ lọ sile ale rẹ.

Eyi mu mi ranti iyawo kan ti mo ni ni ọdun ti o kọja ti o ba ti fẹ lọ sode yio ranṣẹ simi pe ki nfi mọto ranṣẹ si on ti mo ba bere lọwọ rẹ pe nibo ni o fẹ lo? yio sọ fun ni pe on nlọ sọdọ ẹgbọn on ni Eko, ti dẹrẹba ba si de, ti mo ba bere pe nibo ni ẹ lọ, yio si dahun pe awọn lọ si Eko ni, awọn ko tilẹ pe lọhun. sugbọn mọto lo yonu lọna nigbati nwọn nbọ lo jẹ ki nwọn pẹ.

Nigbati o di ọjọ kan ti o sọ pe on yio lo mọto mi ni mo ba gbe fun gẹgebi mo ti ma ngbe fun. Nigbati mo gbe fun ni mo wa lo sọdọ ọrẹ mi, mo lọ ya mọto tirẹ lati lọ fi jadi irọ Dẹrẹba ati iyawo mi na, ọrẹ mi bere lọwọ mi pe nibo ni mọto mi gbe wa? mo si da lohun pe o lọ fun titunnṣe.

Ẹnyin Onkawe mi, bi mo ti nlọ, mo kọkọ lọ si Idi-Oro pe ki nto lọ si Eko ni mo ba ri mọto mi ni ibiti nwọn gbe si.

DẸRẸBA wa ninu rẹ o si ti sun lọ bamubamu mo si ji Dẹrẹba pe nibo ni ẹniti o gbe wa, gbe wa? ati wipe Eko ni ẹ dagbere fun mi pe ẹ nlọ kili ẹ si wa dehin,? nibo ni I Y A W O mi na gbe wa nisisiyi, ni Dẹrẹba juwe Ile kan fun mi ni mo wa lọ si bẹ ki nto jade nibẹ de idi Mọto pada moti ba IYAWO yi pa da ninu mọto, Dẹrẹba ṣebi o sọ fun mi pe ile ọkankan yi lo lọ, mo si wọ ibẹ mi o si ri o. Bayi ni mo ṣe kọ IYAWO yi pẹlu Dẹrẹba yi silẹ. Eyi lo buruju ninu Iwa buruku ti Dẹrẹba sa ba ma nṣe.

Lakotan ẹnyin Okawe mi, Mọto ti DẸRẸBA ba nwa ko ntọ to eyi ti ẹniti o fi Owo ara re ra nwa fun rara-rẹ. Ẹo tun ma gbadun mi to l'ọsẹ tombọ.

## Adojo Omo Ile-iwe sese ninu ija ile-iwe Meji.

SEOUL Ni ilu kan ti anpe ni Seoul, ni iwo orun korea ni agbọ wipe adọjọ ọmọ ile-iwe ni ofi ara sese lọpọlọpọ ninu ija igboro ti o bẹ silẹ larin, ile iwe giga meji ti. wọn nfi igo, ada ọbẹ ati okuta ja. ija yi bẹ silẹ nigbati irinwo (400) ọmọ ile iwe giga kan bẹrẹ si gun ogiri ile- iwe giga keji ti o fara ti. tiwọn ija ajasinu tabi ikun sinu ti wa larin awọn akẹkọ wọnyi. lori ọrọ apapọ ile ẹkọ mejeji. Ọdunrun ọlọpa ni wọn s a r e wa sibẹ. Ṣugbọn ki wọn to le tu awọn onija yi ka itu ti pa ija na ti fẹ rẹ di ogun. ọpọlọpọ ohun ini ni o parun nibi ija yi wọn si fọ ọlọpa kan ṣẹṣẹ pata pata.

Ọpọlọpọ ohun lo sofo loju ija nla yi ohun elo ile ẹkọ gbogbo ni wọn bajẹ bamubamu.

Irohin tun kan wa lati wipe ni ilu kan ti an pe ni anibala ni npunjab enia mẹtala lo ku nigbati awọn ọlọpa fa ibọn yọ ti wọn si bẹ rẹ si yọ lu awọn kan ti w·n nja ija igboro bẹrẹ a gbọ wipe ibọn yinyin yi nigb ti apa awọn ọlọpa ko ka awọn onija yi ohun ti a ·bọ pe o fa ija igboro na ni ọrọ ile ile ẹjọ ti da ẹjọ t le ri pe awọn kan ni o ni ilẹ sugbọn awọn ti o ti wa lori ilẹ na tẹlẹ kọ lati kuro nibẹ. A gbọ wipe ọgbọn enia lo fi ara pa, lẹhin ti awọn mẹtala ti ku, gbogbo awọn ti o fi ara pa si wa ni ile iwosan.

## Awon akeko ti o nkeko nipa ewu.



Awọn ẹniti ẹ nwo ninu aworan yi ni lati ọwọ osi si ti ọtun E. MacFarlane lati ilu Naijiria ti o mba awọn onişẹ ma ẹlẹtiriki şişẹ ni Birnimgham, Robert Ransome akẹkọ ni ilẹ ẹkọ giga ti Birnimgham ati Mensah Dickson lati ghana.

Gbogbo awọn ẹni mẹtẹta yi lo ju mọ nkẹkọ nipa ewu ti yio si wulo fun wọn ti wọn ba fi ilu Gẹsi silẹ lati pada si ilu, wọn. Ninu aworan yi ẹ o ri wipe nişe ni wọn npọn ara wọn lati le gun oke ti o ga kan.

Ile- Ẹkọ ti wọn ti nko ẹkọ yi ni gbogbo awọn akẹkọ agbaye nwa lọdọdun ti Ijọba Gẹsi si nfi owo şe iranlọwọ fun wọn. Awọn akẹkọ si nwa lati ilu okere gẹgẹbi Ghana, uganda, Nigeria, Tangayika, Somaliland, Zanzibar Irag, ati West Indies.

# şile kan pere ra pakęti 'ASPRO' TITUN yi




Paketi "ASPRO" titun yi wa fun tita nisisiyi nibikibi. Şile kan pere ni owo rira rę, koro egbogi "ASPRO" mejilę ni o wa ninu rę. Nisisiyi, ęnikęni le ni "ASPRO" ni ipamo sowo lati ma a lo o ni gbara ti o ba ti ni OTUTU-IBA. O ko le mo igbati OTUTU-IBA yio kolu o tabi ębi rę. Mura silę.
Ra paketi "ASPRO" titun oni şile kan loni!

## 'ASPRO' nda irora OTUTU-IBA DURO


# Ijoba ilu Turkey fe pa Otalelegberun 1500 omo ile - iwe

Lati ilu kan ti a npe ni Akara ni ilu Turkey ļni irohin ti kan wa wipe ijoba ilu yi nfę pa otaleleglberun (1,500) omo ile iwe ti Akęko Ogun (Military College). Ninu iwe ti o ko si awon oga ologun, Olori ogun kan ti a npe ni Gursel so wipe Ijoba nfe pa awon akęko wonyi lati fi da ijoba Ologun ni ęgun ęhin.

Olori Ogun, Ogbeni Gursel yi ni a gbo wipe o şe aşiwaju awon ologun ti won gbe ogun ti ijoba ilu Turkey, ti won si le ijoba lo, ti o je wipe awon ologun ni o gun ori itę ijoba ni ilu yi.

O wi pelu wipe ijoba ti awon le kuro lori oye ati Olotu ijoba na Ogbeni Manders ni ojo kętadilogbon oşu ti o koja yi je awon enia ibi, ti won si jębi lopolopo.

Irohin tun kan wa wipe iwe Irohin kan nilu Turkey ti a npe ni Turkish Press rohin wipe awon nla bi Gomina, Olotu ile işe ijoba (Minister) ati awon aşofin męrindinlogun ni awon ologun ti o wa ni ijoba ti yinbon lu, won si ti mu enia meji ninu awon Ijoba akoko si itimolę.

## Iwe ilana Ifa, Yanrin tite, Etutu Sise, Iwosan ati Egbogi Ajebidan.

Ti o ba ni Iwe yi lowo- Oşo Aiye, Aję Enia - majeki Tenisun won, Alapeta ati awon ibaba ati ikoko ko na lagbara lori rę Ohunkohun ti o ba dawole rere ni yo ma jasi Babanla Awure ati Ogun Ajębidan wa nibę pelu tete ra tirę ki o to tan, awon Babalawopapa wa adura lodo wa ni. Iye Owo 10/6d.

2. Itumo Ala ati Ayewo Odu Ifa 2/6d.
3. Agbara Igba Iwaşę Yoruba ati Psalm Ajębidan 3/-
4. Gbedegbeyo Hausa 2/6 5. Itumo Ami Ara 3/-
6. Ewo Yoruba ati Etutu 3- 7. Ma fomo yomo o

Arofo 1/6d Turari Itaja Adura Tetedamilohun, ati Işegun Aję pelu Psalmu Ajębidan 15/6.

Fi Owo ranse si Ogbeni J.O. Shoyinka 6, Ojo Road (Odunabon) Mushin.

## IDIJE! IDIJE!

Eyi ni lati fi kede fun gbogbo oloye ati omoran papa omo Ibilę Yoruba ti o mo owe yoruba pa, a nfę ogun (20) owe Eniti tirę ba dara ju yio gba poun kan şilekan (£1 ; 1s) Ki se owe ti o wopo ni a nwi o, papa eyiti o ba ję ijilę owe ni a fę o.

Oruko ........................................

Ibugbe ........................................

........................................

Işe ........................................

Ojo ori ........................................

Fi Owe tirę pelu Stamp Toro (3d) ranşe si:-

OLOTU IROHIN IMOLE
16, BAMGBOSE STREET LAGOS.

AKIYESI

A nfẹ Aṣoju ni awọn ilu nwọnyi:- Iseyin, Jos, Ikẹnnẹ, Ọtta, Iwo, Shaki, Kano, Ijede, Aba, Nguru Bauchi, Gbongan, Oshogbo, Zaria, Ado-Ekiti, Fiditi, Ikire, Jẹmi, Bidda.

Mojuba Aiye

A nta oja oniruru to jemọ nkan Ogboni. Bere fun iwe aiye Akamara - Apena, 75 Hausing Street, Surulere Nigeria.
AKIYESI 6th 7th 8th & 9th Books of Moses lede yoruba £1 pete. A le ri ra ni 15, Araoti Street, Yaba Nigeria.

## Akiyesi Pataki

Eyi ni lati fi kede fun gbogbo ẹnyin Onkawe Irohin Imolẹ wipe, ẹnikẹni ti o ba ti kọ Owe Idije tirẹ, ti o si ti fi ranṣẹ, ti ko si fi Stamp tọrọ (3d Stamp) sinu rẹ, ki o tete kọ omiran ranṣẹ pẹlu Stamp tọro ki o si ge Idije sinu rẹ, nitori a ti fa ti akọkọ ya.

Fi owe tirẹ na ranṣẹ ki o le je ẹbun Poun kan silekan £1:1s ẹnikẹni ni o le kọ ọ, ko ba ṣe Ọ m ọ d e, Agba, Onile, Alejo, ko buru Idije yi yio pari ni ipari oṣu yi lagbara Ọlọrun.

Olotu

## Ejo awon Oloye Egba di Osu T'ombo

ADAJỌ V. T. Charles ti o nṣejọ ile ẹjọ gga ti Abẹokuta ti gba lati fi iwe ẹjọ fowo ranṣẹ si Alayelawa Ọ b a Ladapọ Ademọla Alake Abẹokuta ninu aye rẹ gẹgẹbi Alaṣẹ Ake lati fiban idi rẹ ti ile ẹjọ ko fi ni rọ awọn Oloye kan ti Iporo loye.

Eniti o bẹbẹ iwe ẹjọ yi ni Oloye Shodẹmola Owolabi Oluwo Iporo, fun ara rẹ ati awọn oloye pẹlu awọn ara ilu Iporo.

Ọgbeni N. Chukura ati Oloye E. Akinola C o l e nṣagbẹjọro Oloye Owolabi. Wọn ni Alake ti ṣiṣe oipa yiyan Adekunle Coker, ati Yusufu Adebesin gẹgẹbi Oloye, Oluwo, J a g u n a, Apena ati Seriki lehin igbati a ti ti fi to awọn ti o joye wọnyi loye gẹgẹbi aṣa ibilẹ awọn ti o ti joye tẹlẹ ni M a k i n d e Akinjidenwo Ajala Idowu, Tijan Ajibola ati Ọkẹ Shodẹke. Ninu i w e i b u r a rẹ ni ile ẹjọ oloye Owolabi sọ wipe a yan on gẹgẹbi O l o y e Oluwo Iporo ni oṣu Dec, 1956, awọn ti o si yan on le ni ogofa enia ti o jẹ ara ilu Iporo lẹhin iku Oloye Akinwande Thomas.

O ni on dẹ ti ṣe awọn etutu ti o ba oye lọ, o ni on dẹ fun Alake ni Poun mọkanlelogun, a t i Sile mẹwa, ki o to di pe a yan on gẹgẹbi Oluwo. Oni awọn Ogboni gbogbogbo lo dẹ mu on de ọdọ Alake gẹgẹbi aṣa ibilẹ pe Oluwo Iporo ni on nṣe. O oṣu to mbọ ki wọn to bere ẹjọ yi ni gidi.

## Awon Egbe Guide nibi Igbeyawo



AWỌN AGBA EGBE Ọdọ-birin Meji ti Orukọ Ẹgbẹ wọn njẹ Girls-Guide. Omidan N. Rendall ( L o s i ) Balogun iko Kọwa ti Lee South ati Iya-Afin Kathleen Thomas, Bashọrun fun Hendon, ni a ya Aworan wọn ni iwaju Afin Buckingham ni Londonu.

Wọn mu Iwe ti a fi pe wọn si ibi ẹyẹ Igbeyawo Ọmọba Margaret lọwọ. Ogun ninu awọn Ọmọ ẹgbẹ Girls-Guide ni ipa ṣiṣe Igbeyawo yi ti a ṣe ni Londonu laipẹ yi. O yẹ ki a ṣe iranti pe Iya-Iyawo ti o tun nṣe Iya Ọbabirin, Ayaba Elizabeth jẹ Alabo fun Ẹgbẹ Girls-Guide, atipe Iyawo paapa Margaret jẹ ọkan ninu E g b ẹ Girls Guide, o wọ Ẹgbẹ Girls Guide yi ni Ọdun 1937.

OBẸRẸ LATI OJU EWE KẸTA

yi bere lowọ Obirin yi ni ẹmẹta pe njẹ o le ṣe ewọ ogun na? Obirin yi dakun pe on yio ṣe e. Obinrin yi si nṣe gẹgẹbi o ti wi fun. Nigbati Obirin yi ba di korikosun ọkọ rẹ, o wa jẹ iyanu fun awọn ara abule. Awọn Obirin ẹgbẹ fẹ tun mọ wa ni Obirin yi ba mu lo ba alagba yi bakanna si ni alagba yi nṣe fun gbogbo wọn. Ni abule ṣaṣa ba di abule ti o tọ wo di oni o loni.

O digba kan na a o tun ma pade lọse to mbọ lagbara Olorun.

## OBA ni ki orile Ede keke-ke ma nowo. Ninu Idibo

OBA AKENZUA Keji ti I l u Binni sọ ni ọsẹ tok ọ j a yi wipe bi awọn Orilẹ e d e Kekeke ti wọn je japa kuro lara Orilẹ ede nla ba laku wipe awọn ko ni nọwọ ninu Idibo mọ. Ijọba yio suntaki, wọn yio si tun ero wọn pa, nipa ti Ominira Orilẹ ede kekeke.

Ọba Akenzua wi pẹlu wipe awọn orilẹ ede kekeke wọnyi ṣe eyi pẹlu ailebu, ati wipe eniti o ba ṣ ko dara ki wọn yapa tabi lodi si ọrọ na yio jẹ eni abuku a t i alaimoye enia ti o fẹ da ede aiyede silẹ. Akenzua eniti nṣe ọkan ninu awọn O l o t u Ijọba (Minisita) Iwọ-Orun sọ wipe ọrọ yi ti wa nile tipẹ ati wipe ki yio ni iṣoro fun Ijọba bi w ọ n ba le ya orile ede kekeke soto fun anfani gbogbo ile Najiria, ati ki e d e aiyede ma ba ṣ ẹ l ẹ.

